Bibeli fun awon omode



# Oba Dafidi (Apa Keji)

Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Lazarus
Alastair Paterson

Olu'lo: Ruth Klassen

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

Dafidi ni Oba Ilu Juda ni iha guusu Israeli sugbon awon Israeli yooku mu Isiboseti omo Soolu gege bi Oba. Ogun abele di jija fun odun meje sugbon Dafidi di alagbara sii.



Nigbeyin Awon omo ogun re meji pada pa oba Isiboseti.



Nigba naa gbogbo eya Israeli to Dafidi wa won si yan an ni oba lori Israeli. Leyin-o-reyin Dafidi di oba lori gbogbo orile-ede.



Ohun akoko ti oba Dafidi se ni lati bori Jerusalemu. O si di mimo gege bi Ilu Dafidi O si gbero bi agbara lodi si ota; Lati Jerusalemu, awon omo ogun Dafidi jade lati lo bori awon Filistini ati awon ota Israeli yooku.





Leyin naa Oba Dafidi mu Apoti eri Oluwa wa si Jerusalemu apoti eri Oluwa ti o ni ofin mewaa ati awon ofin miran ti a fun Mose lati odo Olorun. Apoti eri ran awon omo Israeli leti nipa ije mimo Olorun ati idi ti won fi nilo lati teriba fun Olorun.

Dafidi ni lati ja opolopo ogun ni ibere isejoba re o je Ologbon Ologun ati onirele okunrin ti o maa n gbadura fun itoni Olorun.





O ko Dafidi
lominu pe oun
ni ibi rere
lati maa gbe
nigba ti Apoti
eri Oluwa
wa ni ibi ago.
Dafidi pinnu
lati ko tempili.
Natani alufaa
Olorun so
fun un lati
tesiwaju.



Loru ojo naa Olorun ranse si Dafidi "Dafidi iranse mi Oluwa yoo ko ile kan fun o. Nigba ti ojo re ba pe, ti iwo o si sun pelu awon baba re emi o si gbe iru omo re dide gege bi oba leyin re Oun o si ko ile fun Oruko mi emi o si fi ite ijoba re kale lailai."

Dafidi fe lati ran iyoku Ebi Soolu lowo O ri omo Jonatani nikan Mefiboseti to je aro “yoo maa jeun ni ori tabili mi gege bi okan ninu awon omo oba” Dafidi ni o wi bee. Dafidi se daradara si Mefiboseti nitori pe o je ore timotimo Jonatani.





Niwon igbati o ti je pe Dafidi gbekele Olorun to si gboran, Olorun ran-an lowo lati se aseyori sugbon lojo kan ojiji buburu dide si aye Dafidi. O ran awon omo ogun re lati ja nigba to ohun duro ni Jerusalemu. Loru ojo kan, ko le sun, nitori o rin lori orule ile re o si n wo gbogbo ilu.

Dafidi ri arewa obinrin to n we. Eni ti oruko re n je Baseba. Dafidi se si Baseba bi o tile je pe oko re Uraya je okan lara akoni omo ogun Dafidi. Nigba ti Baseba so fun Dafidi pe oun ti ni oyun igba yii ni Dafidi to mo pe ese oun ti di isoro nla.







Kaka ki o jewo ese re fun Olorun O gbiyanju lati bo ese re mole. Eyi ko le se e se! O pe Uraya wa sile lati oju ogun nireti pe Uraya yoo ro pe omo ti n bo yoo je ti oun sugbon Uraya ko ni gbe inu ile nigba ti awon omo-ogun re yooku wa ni oju Ogun, Uraya sun si enu ona ile-Oba.

Koda ohun ti Dafidi se buru jai o ran Uraya pada si oju Ogun o si fi iwe le e lowo akosilie naa so pe ki olori ogun rii daju pe Uraya ba ogun lo. Nigba ti won pa Uraya tan, Dafidi fi Baseba se aya.





Olorun ran iranse
re Natani lati fi
ese Dafidi han,
Natani so itan kan
nipa Okunrin oloro
kan ati okunrin
otosi kan.  Okunrin
oloro ni ogorun-un
agutan sugbon
Okunrin Otosi ni
omo agutan kekere
kan eyi ti on sike
re gege bi omo.

Nigba ti awon arinrinajo kan to okunrin oloro yii wa okunrin oloro yii ko pa okan ninu awon agutan re to n toju kaka bee o mu omo agutan okunrin otosi naa o si paa.





Inu bi Dafidi fun iwa imotara-eni-nikan ti okunrin oloro yii hu, o kigbe "okunrin naa ti o se nnkan yii, kiku ni yoo ku."

Alagbara Natani so fun Dafidi pe Okunrin naa ni iwo. Ohun ti Dafidi se buru jai ju nnkan ti Okunrin Oloro naa se lo ninu itan naa.





Olorun fi han Dafidi awon ohun buruku to ti se. Dafidi si ronupiwada ninu ese re. O si wi fun Olorun pe; si eyin Olorun ni mo ti se si ati se ohun buruku yii. Olorun si dari ese Dafidi jin-in.

Sugbon omo Baseba si se aisan o si ku leyin aisan die.



Olorun dari ese buburu Dafidi jin in nigba naa ni Baseba bi omo miiran ti n je Solomoni eni ti yoo di Oba nla leyin Dafidi.  Sugbon oba Dafidi si bi opolopo omo miiran si ninu eyi ti o mu ibanuje nla wa fun-un.

# Oba Dafidi (Apa Keji)

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Samuel Keji ori kin-in-ni titi de ori kejila

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun
iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe: Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.